# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OṢÙ KÉJE, ỌDÚN 2026**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**Ìsìn Omi Iná Ọlọ́dọọdún**

**AGBARA GBỌDỌ PARỌ ỌWỌ - OṢÙ KÉJE, ỌDÚN 2026**

## Ó HA LÈ JẸ́ PÉ

1. **Ó ha lè jẹ́ pé mò n'pín**

Nínú ẹ̀jẹ̀ Olùgbàlà?
P'ó kú fémi t'Ó dá lóró,
T'ó lépa Rẹ dójú ikú?
Ìfẹ́ 'yanu! È há tí ṣe,
Tí 'Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

Ìfẹ́ 'yanu! e há tí ṣe,
Tí 'Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

2. Ohun 'ìjìnlẹ̀! Ọlọ́run kú!

Taní mọ ìdí ète Rẹ̀?
Lásán l'ángẹ́lì ta kọ́ da,
Nfẹ́ mọ, jìnlẹ̀ ìfẹ́ mímọ́!
Ànú ṣá ni! K'áyé júbà,
Kí ángẹ́lì ma wádì mọ́.

3. O f'ìtẹ́ Bàbá Rẹ̀ sílẹ̀,

Ore-ọ̀fẹ́ Rẹ kò lópin!
Ó bọ́ gbogb' ògo Rẹ̀ sílẹ̀,
Ó kú fún 'ran ọmọ Ádám,
Ànú ṣá ni, láìní ìwọ̀n;
L'Ó wá mi rí, Ọlọ́run mi.

4. Ó pẹ́ ta ti de ẹ̀mí mi,
Ṣinṣin l'ó kun ẹ̀wọ̀n ẹ̀ṣẹ̀;
Ojú Rẹ́ tàn 'mọ́lẹ̀ ìyè,
Mo tají, túbú sí mọ́lẹ̀;
Ẹ̀wọ̀n mí bó, mo d'omìnira.
Mo dìde, mo sì ntọ̀ lẹ́yìn.

5. Èmi kò jáyà ẹ̀bi mọ́:
Tèmi ni Kríst, pátápátá!
Mo yè nínú Olórí mi,
A f'òdodo ọ̀run wọ̀ mí,
N'ígboyà mo súnmọ́ ìtẹ́,
Mo gba adé, lágbára Krístì.

## <u>ÀWỌN T'Ó M'ỌLỌ́RUN, Y'Ó MÚ ỌKÀN LE</u>

1. **Àwọn t'ó m'Ọlọ́run, y'ó mú ọkàn le**
Nwọn ó j'alágbára lí ojú ìjà
Èyí n'ìlérí t'Ólúwa ṣe fún wa
Pe á ò ma ṣe iṣé agbára nlá wá

Ìṣẹ́gun, Ìṣẹ́gun
Ìṣẹ́gun t'a f'ẹ̀jẹ̀ rà
Ìṣẹ́gun, ìṣẹ́gun ni ojójumọ́
Jésù Balógùn wa, agbára wa k'yó yẹ̀.

2. Lárìn wàhálà nlá, máṣe sẹ́ 'gbàgbọ́
B'agbára bí aṣẹ́gun n'nú iná 'dánwò

Fi idà Ẹ̀mí rẹ ṣiṣẹ́ agbára
Fa ẹlòmíràn wá, sì yìn Olúwa

3. Jẹ́ alágbára, sì kọjújà s'ọ́tà
Ma yan bí aṣẹ́gun n'nú iná 'dánwò
Fi idà Ẹ̀mí rẹ ṣiṣẹ́ agbára
Fa ẹlòmíràn wá, sì yìn Olúwa.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Gbogbo agbára tó wí pé nkò ní dìde, a ó dá ọ lẹ́jọ́, a ó sì tú ọ ká lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Bàbá, jẹ́ kí ìbínú Rẹ ṣàwárí gbogbo ìdábù aìrí fún àṣeyọrí mi, kí Ó sì mú u kúrò lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo iṣòro olóríkunkun níbi iṣẹ́/òwò mi, ìdájọ́ atòkèwá yóò jó ọ run lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Olúwa, dìde lónìí, kí O yí dànù gbogbo irètí tó lòdì nípa ayé mi, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti gbógunti àwọn olùránlọ́wọ́ ayànmọ́ mi, ìwọ yóò gba ìdájọ́ atòkèwá lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá, jẹ́ kí àṣírí gbogbo ètò ìkọ̀kọ̀ tó lòdì sí ọjọ́ iwájú mi tú síta lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo májẹ̀mú búburú tó n yọ ayànmọ́ mi lẹ́nu yóò fọ́ nípa ìdájọ́ atòkèwá lónìí, ní orúkọ Jésù.

## **ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ**

**Deuterónómì 20:4:** Nítorípé OLÚWA Ọlọ́run nyín ní mbá nyín lọ, láti bá àwọn ọ̀tá nyín jà fún nyín, láti gbà nyín là.

**Isàíàh 41:13:** Nítorí Èmi Olúwa Ọlọ́run rẹ yóò di ọwọ́ ọ̀tún rẹ mú, èmi Ó wì fún ọ pé, Má bẹ̀rù; èmi Ó ràn ọ́ lọ́wọ́.

**Orin Dáfídì 108:13:** Nípaṣẹ̀ Ọlọ́run li àwa ó ṣe akin; nítorí Òun ni yóò tẹ àwọn ọ̀tá wa mọ́lẹ̀.

**Jóṣúà 10:8** OLÚWA sì wí fún Jóṣúà pé, Má ṣe bẹ̀rù wọn: nítorítí mo ti fi wọ́n lé ọ lọ́wọ́; kì yóò sí ọkùnrin kan nínú wọn tí yóò lè dúró níwájú rẹ.

**Málákì 4:2:** Ṣùgbọ́n Òrùn òdodo yóò là, ti òn ti ìmúláradá ní ìyẹ́-apá rẹ, fún ẹ̀nyin tí ó bẹ̀rù orúkọ mi; ẹ̀nyin ó sì jáde lọ, ẹ̀nyin ó sì ma dàgbà bí àwọn ẹgbọrọ̀ màlú inú agbo.

**Isàíàh 53:5:** Ṣùgbọ́n a ṣa a lí ọgbẹ́ nítorí ìrékọjá wa, a pá á lí ara nítorí aìṣedédé wa; inà alàfíà wá wà lára rẹ̀, àti nípa inà rẹ̀ li a fi mú wa lára dá.

**Orin Dáfídì 118:24** Èyí lí ọjọ́ tí Olúwa dá: àwa ó ma yọ̀, inú wa yóò sì ma dùn nínú rẹ̀.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Olúwa dìde, pa gbogbo ẹ̀mí ìdáyàfò run nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ìdábù olóríkunkun níwájú àwọn ìyanu mi, di mímú kúrò báyìí, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá, dojúkọ gbogbo agbára tó n jí gbogbo anfàní mi, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ìdádúró ẹ̀mí òkùnkùn tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi, gba ìdájọ́, kí o sì parun, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa dìde, fọ́ gbogbo àjàgà ọlánrẹ́yìn nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

**ÀDÚRÀ SÓRÍ OMI**

1. Bàbá mi, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún ṣíṣẹ̀dá omi gẹ́gẹ́ bí lára àdìtú àrà iṣẹ̀dá Rẹ. Olúwa, Ẹ ṣeun nítorí omi jẹ́ ààmí Ẹ̀mí Mímọ́. Omi n fọ̀ nkan, ó n sọjí, tẹ́nilọ́rùn, sọdọ̀tun, mú dúró, wẹ̀mọ́, ó sì tún jẹ́ amú-nkan-dàgbà.
2. Olúwa, dìde nípa agbára Àjínde Rẹ, kí O sì mín èmí Rẹ sórí àkójọpọ̀ omi yîi. Jẹ́ kí iná Ẹ̀mí Mímọ́ ṣíjibo omi yìí, kí O sì sọ ọ́ di iwòsàn atòkèwá, omi iṣẹ̀dá, omi tó n rún ẹ̀mí òkùnkùn mọ́lẹ̀ wómú-wómú, ajíra atòkèwá àti egbòògi aporó atòkèwá, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá mi, jẹ́ kí ohun gbogbo tó mbẹ nínú omi yìí gbé iná tíkò ṣe é pa, èyí tí yóò dójútì gbogbo irúgbìn òkùnkùn nínú ẹ̀jẹ̀ mi àti ní gbogbo àgọ́-ara mi pátápátá, jẹ́ kí ó pèníjà gbogbo májèlé tó farasin nínú ara mi, kí o sì tì í jáde, ní orúkọ Jésù.

4. Bàbá Olúwa, bí n ó ṣe mu omi yìí, jẹ́ kí agbára omi ìyè dàpọ̀ mọ ọ, jẹ́ kí ó sọ ìgbà èwe mi di ọ̀tun bí ti idì; jẹ́ kí ẹ̀mí ọgbọ́n, ẹ̀mí òye, ẹ̀mí imọ̀ràn àti ẹ̀mí ipá, ẹ̀mí ìmọ̀, àti ẹ̀mí ibẹ̀rù Olúwa bàlé ayé mi, ní orúkọ Jésù
5. Olúwa, bí n ó ṣe mu omi yìí, jẹ́ kí ó fọ gbogbo ìrúgbìn òkùnkùn kúrò nínú ayé mi, jẹ̀ kí ó nù kúrò ibànújẹ́ àti omi ìkorò tó n dàmú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
6. Agbárákágbara tó n tako erèdí àti ètò atòkèwá Ọlọ́run fún ayé mi, di ṣíṣí dànù nípa omi iná yìí, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí omi yìí túká gbogbo ìwo òkùnkùn tí wọ́n gbìn lòdì sí ayé mi, jẹ́ kí ó pa gbogbo pẹpẹ tí wọ́n gbé kalẹ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi l’áyiká mi run, ní orúkọ Jésù.
8. Ìwọ omi yìí, wẹ aìsàn, àmódi, aìlèra àti àrùn títí dójú ikú jáde kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
9. Ẹ̀yà ara tóti dòkú ìyówù nínú àgọ́ ara mi, gba ìyè nígbà tí o ba bá omí iná yìí pàdé, ní orúkọ Jésù.
10. Bàbá, jẹ́ kí omi iná yìí tú ìwà-ìkà olóríkunkun àti àjẹ́ olóríkunkun ní àgbègbè mi ká, ní orúkọ Jésù.